WEEKS 32 & 33
Kongi WK 32
23, 24, 31,
WK 33
10 11 19
Asko Bks Wk 32
14 18 24 29
WK 33
22 28 30 31
Ross Wk 32
3 & 9
WK 33
17&43

IBADAN.
5/3/77
IBADAN UNIVERSITY LIBRARY
10 MAR 1977

# Imọlẹ Owurọ

EṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

UNITY NAP

For 3 sure bankers for wk 33 send ₦5 to E. O. Adeyemi c/o P. M. B. 5230 or come to Imọle Owuro Office Ib.

**5, 22, 45 nap**

Independent Paper Vol. XV NO 788 SATURDAY MARCH 5— FRIDAY MARCH 11, 1977 10K. (KOBO MEWA)

# YANMUYANMU DA HUOHUO SILE NI LỌKỌJA

IRU awọn ẹfọn kan (yanmuyanmu) ti nwọn sọ pe, nwọn ko riri, ti ya wọ tiletoko Lọkọja ni Ipinlẹ Kwara, nwọn si ti da huọhuọ silẹ.

Irohin ti o tẹ wa lọwọ lati ilu na fi ye wa pe, yun-un ni awọn ẹfọn na ngba, ti nwọn si nja awọn ara ilu l'ogun.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, ẹfọn na ti sọ ọpọlọpọ enia di alarun iba ni ilu na awọn diẹ na ni o si ti ku patapata nipa ikọlu awọn ẹfọn na.

A gbọ pe nitori agbako awọn ẹfọn na, awọn ara ilu nsare lọ ra apo ẹfọn, sugbon apo ẹfon na ko di awọn ẹfọn na lọwọ.

Ẹnikan ninu ilu na fi ye wa pe, oun ko ri iru awọn ẹfọn na ri lati ọjọ ti oun ti dele aiye nitoripe o l'oju oogun ẹfọn ti enia le fin si wọn ti o le pa awọn ẹfọn na.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, o fẹrẹ ma si ile kan ti alaisan ẹfọn ko si ninu rẹ nilu Lọkọja; bẹẹ ni gbogbo oogun ti nwọn fi nfin ẹfọn ti nbẹ nilu Lọkọja ni nwọn ti ra tan ati pe lati Ilọrin ni nwọn ti tun nlọ ko

(Woju Ewe Kejo

## Kiko Aafin Sohun Ogbomoso

FACE ONE FINAL LAUNCHING FUND OF ṢỌHUN'S PALACE.

EYI ni lati kede pe ni ọjọ kẹsan oṣu kẹrin ọdun yi (9/4/77) ni a o ṣe aṣepari ikowojọ fun igbesẹ kinni lori eto kikọ Aafin Ṣọhun Ogbomọṣọ, eyi ti yio waiye ninu Gbọngan ilu Ogbomọṣọ ni deede agogo mẹwa owurọ.

Gbogbo enia ni a pe nile, l'oko ati ni idalẹ. Ẹ ma ṣe alaiwa o nitoripe "Aṣetan ni i mu iṣẹ ni oriyin".

IGBIMỌ IKỌLE
(Olukede)

## IKEDE PATAKI

GBOGBO awọn Agbintaba ti nwọn ba fẹ darapọ mọ Ẹgbẹ Kajọla titun nibikibi ti nwọn le wa: Ogbomọṣọ, Ejigbo, Iwo, Ọyọ, Ilobu, Ikirun, Ilọrin, ati bẹẹbẹẹ lọ. Ki nwon tete kowe tabi wa fojukan:

OLOYE VICTOR LAJIDE,
OLUDASILẸ KAJOLA TITUN,
P. O. BOX 44, OGBOMỌṢỌ

Lagbara Oluwa, anfaani Ẹgbẹ titun yi yio ju ti Monigbagbe 1964 lọ. Ki i ṣe lori taba nikan ṣugbon lori oriṣirisi ona ti yio mu ilọsiwaju ati anfani ba awon ọmọ Ẹgbẹ.

## Ijo Selesia kowe si Imole Owuro

IJỌ Aladura ti njẹ Celestial Church of Christ ti adugbo Yemẹtu nilu Ibadan, eyi ti a tẹ irohin rẹ jade ninu iwe Imọlẹ Owurọ ọsẹ ti o kọja, ti kọwe kan si ile iṣẹ iwerohin na l'ori irohin na.

Ninu irohin iwe ọsẹ ti o kọja na, bi a ba ranti, ni o ti jade pe "Ṣọọṣi Sẹlẹsia yari mọ Iya-Ijọ wọn lọwọ" pe, awọn ko fẹ Iya Ijọ na mọ nitori ẹsun ẹṣẹ kan ti nwọn ko darukọ ti nwọn fi kan an pe o da.

Ṣugbọn ninu iwe ti Ijọ na ti ọwọ Alagbẹjọro wọn, Amofin S. Ọla Fatungaṣe kọ, Ijọ na sọ pe irohin inu iwe Imọlẹ Owurọ na kọ awọn l'omnu pupọ. Nwọn ni ibalorukọjẹ ni irohin na jẹ ati pe, "ko si ododo kan ninu rẹ".

A o ranti pe ninu iwe wa ọsẹ ti o kọja na, a sọ pe gbogbo akitiyan wa lati ri Iya Ijọ na lati gbọ ti ẹnu rẹ ko bọ si i.

Bakanna, gbogbo akitiyan onirohin wa lati ri Baba Ijọ na lati gbọ bi ọrọ na ba ti jẹ ko tii bọ si i pelu.

(Woju Ewe Kejo)

## Eto agbayanu fun Ogbomoso

ALAGA Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ogbomọṣọ, Oloye Victor Lajide ti sọ pe, eto ilọsiwaju yio bẹrẹ ni akọtun fun ilu Ogbomọṣọ laipẹ.

Ki eyi ba le ṣe i ṣe, Oloye Lajide sọ pe, oun ti paṣẹ fun awọn Kansilọ oun pata lati tete jẹ ki Kansul oun mọ ohun gbogbo ti awọn enia aaye idibo wọn ba nfẹ nipa kikọ ọ sinu iwe ṣọwọ si ile iṣẹ Kansul na.

Nigba ti Oloye Lajide ndahun ibeere kan lati ọdọ oniwerohin, o ni ọna lila, fifun ni l'omi ẹrọ ati mimu anfani ina de ibi ti ko de yio jẹ ohun akọkọ ti Kansul

(Woju Ewe Kẹjọ)



OLOYE VICTOR LAJIDE
Alaga Kansul Ogbomọṣọ

# ATIORO ỌMỌ ATIALA

## A ! ENIYAN (5)

A sọ fun nyin
L'ọsẹ t'o kọja
Nipa ẹni t'o lowo,
T'o fi nran
Ọmọ araiye lọwọ;
A sọ b'o ṣe ngbero
Pe, kemọnikeji d'eeyan.
A si sọ
B'o ṣe gbiyanju
T'o j'aiye ẹlomiran o d'ire;
Gbogbo rẹ la wi
Ti a ti ro silẹ.
Wayi o:
Ẹ tara wa gbọ
Ohun t'o ṣelẹ
Lẹhin oore
Ti ọmọ ọlọmọ ṣe.
Gbogbo ẹni t'o ṣe l'oore
L'o yara
T'o yọwọkọwọ;
Ko pẹ, ko jinna,
Nwọn yọ 'wakiwa.
Owo nlanla,
Aṣọ nlanla,
Ati ọrọ nlanla ni




Awọn eniyan yi lo
L'ori ọmọ ọlọmọ
T'o ṣe wọn l'oore !
A ! Aiye ree o !
Gbogbo ẹni ti ngbọ wa,
Aiye ! Eniyan,
Ẹni a ṣe loore waa mu
Owo nlanla
O mu un rele onifa !
O mu agutan bọlọjọ
O mu re'le onişegun;
O mu agbada aran,
O mu t'ẹtu danwo;
O ni k'onişẹ ibi tara
K'o b'oun ṣe e nibi
Nitori pe,
" Akukọ gagara l'o jẹ
Ti ko jẹ ki
T'ilẹ o lẹ kọ ni"
K' iṣegun o tete kia
K'o b'oun gb'ẹmi 'ẹ !
Ṣe nitooto,
Onit hun lowo
T'o k·ja t'ẹni t'o lowo;
O hẹrẹntẹ l'aiye
O ju ti
Gbogbo adugbo;
Koda, bi
Gbogbo eniyan
T'o ran lọwọ
Ti tobi to,
O tun tobi ju
Apapọ gbogbo wọn lọ;
Eyi l'o fa idi ọrọ
Ti gbogbo
Ẹni t'o ṣe l'oore
Fi pẹyinda,
Ti nwọn fẹ gb'ẹmi ẹ
kinnikan nbẹ
Ṣe
Ti ko ye ọpọ
Ọmọ araiye;
Nwọn ko mọ pe
Bi a ba nṣe nṣe oore to,
L'oore ṣe e knnle ẹni;
Bi a ba si nṣika,
Ika ki i wọn ni
Nigbakigba;
Eniyan t'o l'oju aanu
S'ọmọ Aadamọ l'aiye,
Ọlọrun Ọba Ọrun
Ni i gbe wọn i ga;
Ko si baba oşika
T'o le sọ wọn d'ero ilẹ.
Bẹẹ b'eniyan ba nşaanu,
T'o ba nşoore
T'o ba Ọlọrun nile,
Walahi-talahi
Aala ngbọ:
Oore Oluwa
Ko ni i dawọduro
L'ori iran Oloore
Ayamọ b'o ba ṣe
Pe, oluwarẹ tun şika.
Ẹ jẹ k'a pa yi ti na
Gbogbo ara ibi;
Ẹ jẹ k'a maa ba
Nasia wa lọ.
Nwọn sa ewe titi
Ewe kọ,
Ewe ko jẹ !
Nwọn sa oogun, sa oogun,
Ogun kọşa
Ko tilẹ dahun;
Ọmọ araiye ni;
B'oogun ko ba jẹ
Ẹnu yio si jẹ
L'ara ẹni ti nwọn fẹ pa;
Nwọn ni;
Ko s'eeyan ti
Ẹnu yio pa ti
Ninu awon adarihunrun
Nitoripe:
Ẹnu mu ju abẹ lọ,
Ọran l'ẹnu eniyan.
Nwọn wa bẹrẹ irọ,
Nwọn bẹrẹ eke,
Nwọn nparọ mọ
Onitọhun lau
Lai ṣe wọn n'ibi;
Awọn ika eniyan,
Ti nãbiyanju
Lati şiwọ oloore re delẹ!
Bayi l'aiye ri o
Gbogbo janmaa wa,
Bẹẹ l'eeyan ri
Gbogbo janmaa.
Eniyan ti ntoşi
Ti a sọ d'ọlọrọ
Lai wẹhin:
Ẹni oju npọn
Ti a pakiti mọri
Ti a sọ d'ẹni giga:
At'eeyan ti njiya
Ti a yọkuro ninu iya,
Lai gba obi,
Lai gba nkankan,
Şugbọn t'o wa pẹhinda
T'o mu ninu
Oore ti a ṣe e.
T'o fi d'oju ibi kọ ni !
Ti ko fẹ k'a nilaari,
Ti ko fẹ k'a pataki
Ti ko fe
K'a ju oun lọ !
Ti ko fẹ k'a to oun,
Ti ko si fẹ
K'a gbe aiye mọ !
Taa l'o tun ku
Ti ko mọ aiye ?
Aiye ree o, Eniyan!
L'ọse ti nbọ
A o bẹrẹ Nasia titun.
T'o fara pẹ ara wọn.

ỌLỌLA ATIORO

# Ahunso Naijiria gbodo hunso ti o dara

## —Olaosebikan

ONIŞOWO omo ile Naijiria kan ni Ipinlẹ Oyo ti nta orisirişi aşo Ọgbẹni Emanuel Ọlaniyi Ọlaoşebikan, ti kesi awon ile işẹ ti nhun orişirişi aşo ni ilẹ Naijiria lati şe atunşe l'ori awon ohun elo ti nwon fi nhun aşo, eyi ti yio jẹ ki iru aşo bẹẹ ni alopẹ

Ọgbẹni Ọlaoşebikan pe ipe yi ninu ile itaja aşo rẹ ni aarin ojule Abudu ni Gbagi nilu Ibadan nigba ti o nşe apero bi ojo ola yio şe dara l'ori oja aşo tita ni ilẹ Naijiria.

O so pe, bi o tilẹ jẹ pe opolopo iyipada l'o ti wa l'ori işẹ owo aşo tita lati igba ti Ijoba Ologun Apapo ti gbe ofin "Faaye gba omo onile" jade, orişirişi aşo ti awon ile işẹ aşọ hihun ni ilẹ Naijiria nşe jade l'o ku diẹ kiato fun.

Ọgbẹni Ọlaoşebikan şalaye pe, ki eto "tinwa-ntiwa" ti awon Ijoba ilẹ Naijiria nşe le fidi mulẹ daradara awon ile işẹ aşo hihun ni ilẹ wa gbodo şe atunşe l'ori awon aşo ti nwon nhun bii ankara, leesi, ginni, borokeedi ati bẹẹbẹẹ lo ti yio fi jẹ pe nwon yio le maa ni alopẹ gẹgẹbi awon aşo hihun ti nti ilu Oyinbo wa.



ỌGBẸNI ỌLAOSEBIKAN

Ninu ibere kan lati odo awon onirohin; Ọgbẹni Ọlaoşebikan fesi pe anfani ati igbadun awon onibara awon lo jẹ awon l'ogun ati pe nitorina ni awon şe kesi awon ile aşo hihun lati ba won mojuto awon ohun elo ti nwon nlo ki aşo ti nwon nhun ba le dara:

O fi kun un pe, aşo isenbaiye bi ofi, sanyan ati alaari ni oun fi bẹrẹ işẹ owo aşo tita ati pe opolopo ipinlẹ ni ilẹ Naijiria ni oun ti şişẹ na de ki oun to şi ile aşo tita n'ilu Ibadan.

Ọgbẹni Ọlaoşebikan so pato pe looto, aşo ni iyi ara ati pe ki oro aje Naijiria le losiwaju, awon aşo hihun ti ilẹ wa nhun gbodo yege daradara gegebi ti ilu okere ni.

# Enia meji kagbako l'abule Itori

ENIA meji ototo—okunrin kan ati obinrin kan ni nwon sare gbe lo si ile iwosan Abẹokuta ni Ipinlẹ Ogun ninu osẹ yi nigba ti okunrin gende kan dede fa ada yo ni abule Itori ni ilẹ Ẹgba, ti o si şa awon enia na ni işakuşa.

Irohin lati ilu Abẹokuta fi ye wa pe, nşe ni ori okunrin na yi.

Gẹgẹ bi a ti gbo, okan ninu awon enia na ti işe obinrin gba ọgbẹ pupọ tobẹẹ ti o fi jẹ pe, ẹsẹ kan aiye ẹsẹ kan orun ni o wa ni ile iwosan bayi.

Nwon ni eyi ti o jẹ okunrin gba ogbẹ ni atari ati ẹsẹ. Oruko okunrin ti o gbogbẹ na ni Lateef Olulẹyẹ.

Bayi, a gbo pe awon Ọlopa ilu Abẹokuta ti tojubo oran na.

# Ẹgbọ́ t'ẹmi

## Akuko ko Ko mo !

OLOOTU,

AKUKỌ ko ma kọ mọ l'ode oni o, abo l'o nkọ !

Ohun ti o jẹ ki ng sọ bẹẹ ni pe, awọn obinrin Kọngiratọ l'o nri iṣẹ gba ju ọkunrin lọ l'ode oni. Iru iṣẹ ti o wu ki o le jẹ, obinrin l'o nri i gba ju ọkunrin lọ.

Ohun ti o wa buru ju nibẹ ni pe, ọpọ iṣẹ wọnyi ni awọn obinrin wọnyi ko le ṣe ti o jẹ pe, nṣe ni nwọn tun maa ngbe e fun ọkunrin ṣe ! Olootu, ẹ ko ri i pe nkan ki s'ẹsẹ rago ?

Nipa bayi, ọpọ obinrin ni o ti lowo lọwọ ju ọkunrin lọ; idi si niyi ti ẹnu ọkọ ko fi ka ọpọ obinrin ninu ile, ati ti ọpọ obinrin ko fi ba ọkọ wọn gbele pelu.

Nitorina, mo kesi Ijọba Ologun Apapọ lati paṣẹ pe ki nwọn maṣe gbe iṣẹ pupọ fun obinrin mọ nitoripe owo ti nwọn nni ju ọkọ lọ ko jẹ ki ẹnu ọkọ ka wọn ninu ile.

Emi ni,
Ọkẹ Ọmọyajowo,
Ebutemẹta.

# 24 25

## Asakasa l'eyi

OLOOTU,

O ti di aṣa awọn ọmọ ode oni, paapaa awon alakọwe lọkunrinlobinrin lati maa daṣa pe, awon nlọ jẹbọ nibikan.

Bi o ba ṣe pe ori awọn enia ti ndaṣa na pe ni, o yẹ ki nwọn mọ pe ohun irira niwaju enia ati Ọlọrun Ọba ni ,'ẹbọ'' jẹ, bẹẹ ni ko dun i gbọ l'eti pelu.

Bawo ni enia kan ṣe nilati jẹ alaimọkan to, de ibi ti o fi npe ounjẹ ti yio jẹ si enu ara rẹ ni ẹbọ ?

Olootu, ṣe akọ na ni nwon nṣe to bẹẹ ni tabi nṣe ni o jẹ pe nwọn ko mọ iyatọ laarin " ẹbọ " ati ounjẹ pe, ounjẹ ni enia njẹ, "ẹbọ" ni nwọn si nru fi ṣe etutu, enia ki i jẹ ẹbọ o.

Emi ni,
Iṣọla Adeaga,
Ọyọ

AKIYESI

Ọgbẹni wa Iṣọla,
Awa na ro pe o nilati jẹ pe nwọn nṣe akọ ni tabi pe nwọn ko mọ iyatọ laarin ẹbọ ati ounjẹ. Ṣugbọn ohun ti a ri nipa iwa ọmọ enia ni pe, ọpọ l'o maa nṣe nkan nitoripe "aiye nṣe bẹẹ" lai ni i ronu bi o dara tabi ko dara; bi o pe oun tabi ko pe oun. Nitorina maṣe jẹ ki o ya ọ l'ẹnu.
—OLOOTU.

## Iya Omi nje wa ni Agege

OLOOTU,

Ẹ dakun ẹ gba mi l'aye lati kesi Ijọba Ologun Ipinlẹ Eko lati ko wa yọ ni Agege nibi ọwọngogo omi ti o nda wa laamu nibẹ.

Omi wọn pupọ ni Agege tobẹẹ ti o jẹ pe Naira kan ni a nra garawa omi kan nibẹ. A gbọ ti nkan yoku ti o wọn, ṣugbọn ti omi yi ni o mumu ni aiya wa ju.

Nitorina, a nrọ Ijọba Ipinlẹ Eko lati jọwọ ko wa yọ ni Agege o.

Emi ni,
Samuel Ajibade,
Agege.

## Awon Olote tun de !

OLOOTU,

ẸNU ọjọ mẹta yi ni gbogbo enia ndupẹ lọwọ awọn oṣiṣẹ Adiyelọja fun ọwọ gbigbona ti nwọn fi mu awọn elere ajeju ni ilẹ wa, nipa eyi ti owo awon ọja kan fi lọ silẹ diẹ.

Sugbọn bayi, awọn "Ọlọtẹ" ti tun de ! Nwọn ti bẹrẹ iṣẹ wọn lati ba aniyan awọn Igbimọ Adiyelọja jẹ.

Lati bi ọsẹ melo kan wa ni a ko ti ri Miliki ti nwọn npe ni "Peak Milk" mo l'ori atẹ !

Ṣe, awon ti nṣe e ko ṣe e mo ni tabi awon ti o nko o wa Naijiria ni ko ko o wa mo ? Tabi pe, ṣe awon ti npin oja na ni o ntaa ni owo gege sibẹ ni tabi awon alagbata ni o nko o pamo ti nwon si nyo o ta ni dosinni kookan ki nwon ba le jere ajẹju ?

Ki l'o fa a o ? Tabi awon "Ọlotẹ" tun bẹrẹ iṣẹ won ni ? Bi o ba ri bẹẹ, mo ro Igbimo Adiyeloja lati ba ni tojubo oran na kiakia.

Emi ni,
Suarawu Adisa,
Ibadan.


# GBANGBA ẸWA!

₦405.00



GBANGBÁ ẸWA—Alupupu Suzuki A100

Fun agbara ti o ni, ati igbẹkẹle ti o ki—GBANGBÁ ẸWA—SUZUKI A100
Fun irọrun ati ẹwa ti o gbamuṣe—
GBANGBÁ ẸWA—SUZUKI A100.
O ni agbara pupọ, ko si iye ti o ngba fun itọju.

Ko sirọ nibẹ, alupupu
Suzuki 'A100' jẹ GBANGBÁ ẸWA

SUZUKI Ra ohun to yẹ ọ.

# Akédé ọnà Iyè

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# Iwo ha npe ibi ni rere bi? (1)



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"EGBE ni fun awọn ti npe ibi ni rere ati rere ni ibi. Ti nfi ikoro pe adun ati adun pe ikoro. Egbe ni fun awọn ti nwọn gbọn li oju ara wọn, ti nwọn si mọ oye li oju ara wọn" Isaiah 5: 20-21.

Dajudaju, ki ba ti pẹ ti imọlẹ ki ba ti wa ninu aiye ju igba ti oju wa ṣẹṣẹ nla yi lọ ṣugbọn awọn ti a npe ni Baba wa l'aiye atijọ l'o faa. Awọn l'o fa a nitoripe nwọn gbọnju l'oju ara wọn tobẹẹ ti ọpọ ninu wọn fi ni igbagbọ pe ko si aiye miran t'o tun le dara ju aiye tiwọn lọ.

Aiye wo si ni aiye wọn ti o dara nigbana? Aiye ti ọmọ nrin ihooho ti baba nwọ ibantẹ? Aiye ti awọn ajẹ ngba ọmọ lọwọ iya rẹ ti nwọn ngbe pada fun un l'oku?

Ani aiye wo ni aiye awọn baba wa? Aiye ti Ọba ilu nra ẹiyẹ ajẹ jẹ tobẹ ti ki yio fi gbọ ọrọ Ọlọrun l'ẹnu enia kankan afi ẹni ti o ba njuba igi ati okuta ? Aiye ti ọpọ maa nrin ninu igbo titi ti nwọn fi maa npade iwin ti o ngbe inu igi.

Awọn iwin ti nwọn ba pade bayi jẹ ara ẹmi okunkun aiye— ani iranṣẹ eṣu ti Ọlọrun ti le sinu aiye. Awọn wọnyi ni ọmọ aiye yi sọ di alagbẹkẹle wọn! Nwon nba ọta Ọlọrun Ọrun oun aiye ṣe ọrẹ !!

Awọn iwin wọnyi ni o maa nsọ fun wọn pe ko si aiye miran ju ti ọdọ wọn lọ. Awọn ni nwọn maa nkọ oogun buburu l'ọdọ iwin ti iwin yio si maa sọ fun wọn pe, ki nwọn sa maa juba igi toripe inu igi ni awọn ngbe.

Ọpọ iwin miran a maa sọ fun wọn pe ki nwọn maa juba okuta toripe ọpọ iwin ni o maa ngbe abẹ okuta. Ara iba awọn iwin na ni nwọn maa npe ni "Iba pẹlẹbẹ atẹlẹsẹ" nitoripe tọwọtẹsẹ ni nwọn maa ndabolẹ wọ abẹ okuta na lati lọ gba agbara.

Gbogbo awọn iwin wọnyi ni nwọn ni ede ti nwọn ti maa nba ẹranko sọrọ; eyi ti o fi jẹ pe ọdẹ ti o ba mọ oju iwin ki i wa ẹranko ti ninu igbo ọdẹ, ko si si enia ti o le moju iwin ki Ọlọrun tun jọ oluwarẹ l'oju nitoripe agbara awọn ẹmi okunkun na ni yio gbẹkẹle.

Bẹẹ gẹgẹ ni enia ko jọ iwin loju paapaa nitoripe ẹranko ni nwọn ka enia si. Nigba ti awọn iwin ba fẹ ṣe ariya oro wọn, awọn ẹranko ni nwọn maa nyan ni Alaga nigbati nwọn yio ti sọ fun ẹnikan ninu awọn enia ti o ba nba wọn ṣe ipade lati ba wọn wa enia ti awọn yio lo fun etutu ti awọn fẹ ṣe; "ni aiye". Irin iṣẹ eṣu ni wọn gẹgẹ bi a ti ntẹnumọ ọn, nwọn si ni igbagbọ pe ko si bira ti awọn ko le da ninu aiye ati pe ko si itu ti awọn ko le pa. Bi nwọn ba si ri ẹni ti ko gba agbara eṣu bii tiwọn nwon a ni "Oluwarẹ ko mọ aiye".

Orişirişi awọn ẹranko l'o ni agbara eṣu lọwọ l'aiye tobẹẹ ti o fi jẹ pe bi awọn enia t'o ba fẹ di oloogun ba lọ ba awọn iwin wọnyi lẹhin ti nwọn ba ti fun un ni idanwo orişirişi to si bori idanwo na, o le maa wa wo wọn ni ọganjọ oru, nwọn a si bẹrẹ ni iwin npe bẹẹ) pe, ṣe nwon ko ti i tọ le ori ewe bayi-bayi. Ti nwon ba da a lohun pe awon ko ti i tọ le e, nwon a ni ki o lọ ja a pe, ti o ba fi wẹ tabi fi i si oju egbo, kia ni egbo na yio san tabi pe kia ni oluwarẹ yio san ninu aisan yowu ki o le maa ṣe e.

Bayi ni awon iwin sọ ọmọ enia di ẹranko nipa wiwa agbara kiri l'aiye lai mo pe otitọ ati ododo ni ohun gbogbo nba ṣiṣẹ.

Njẹ, ki l'o wa jẹ ki ọpọ awọn agba aiye atijọ ṣofo danu ti nwọn

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

orukọ ti awọn iwin maa npe enia ni Adarihunrun.

Ninu gbogbo agbara ti awọn ẹranko ẹiyẹ nlo ninu igbo, ko si eyi ti iwin ki i lo. Nwọn le fo bi ẹiyẹ, nwọn si le bẹ bi ẹdun.

Gbogbo agbara ẹranko wọnyi ni nwọn fi maa nta enia t'o ba njuba wọn l'ọrẹ. Nitori gẹgẹ bi a ti kọ sọ, irinṣẹ eṣu ni wọn, nwọn ko mọ Ọlọrun bikoṣe eṣu, inu wọn a si maa dun si enia ti o ba ni igbagbọ si iṣẹ wọn.

Ni aiye atijọ ti a npe ni aiye awọn "baba-nla" wa aiye yi, ni awọn enia ti o ba moju awọn iwin wọnyi, ti nwọn si ti gba oniruuru agbara ẹranko lọwọ awọn iwin, maa nyangan l'ọdọ awọn enia nlanla ti o ba jẹ olowo pe awọn yio ṣe oogun fun wọn ati bẹẹbẹẹ lọ.

Nipa agbara ẹiyẹ ti nwọn ni, nwọn a maa rin l'oru; bi idagiri ba si de, nwọn a fo lọ. Idi niyi ti awọn ti nwọn ti gba agbara ẹranko wọnyi fi maa npe ara wọn si i ko gbogbo awọn oogun buburu gbogbo fun un

Awon ti a pe ni oogun yi ki iṣe pe, ohun ijinlẹ kan wa ni idi rẹ bikoṣepe, iwin ni yio beere owo awon ẹranko (enia ko si ni oruko rere? Tete ra iwe irohin Imọlẹ Owurọ l'ọsẹ t'o nbọ lagbara Jesu Kristi.

ADURA

Oluwa, ma ṣe fun mi lagbara lati sin ohun gbogbo t'o yapa si ifẹ Rẹ, Aamin,


## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣowo si nyin ni aadota Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.


ADÍRẸSI OLÓOTÚ

LOOTU,
IMOLE OWURO,
P.M.B. 5230,
IBADAN


## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyọkan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
(1) N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin

## Opaleye sinmi l'enu ise

ONIRUURU ayẹyẹ ifẹhinti l'ẹnu iṣẹ ni nwọn ṣe fun Diakoni Rowland Akanni Ọpalẹyẹ ti o ṣẹṣẹ fẹhinti l'ẹnu iṣẹ Ọba. Ni ilu Zaria l'Oke Ọya ni ayẹyẹ na ti waiye.

Ọdun mẹẹdọgbọn ni Diakoni Ọpalẹyẹ l'o nilu na ki o to fẹhinti l'ẹnu iṣẹ. Ile iṣẹ ti nje Nigerian Civil Aviation Trainning Centre nilu Zaria ni o ti nṣiṣẹ.

Ki o to wọ ibi iṣẹ ti a nwi yi ni o kọ ti ṣiṣẹ ni Zaria Native Authority Works Department nilu Zaria.

Bakanna ni Diakoni Ọpalẹyẹ ko mẹẹri ninu iṣẹ Ijọ Ọlọrun o si ti jẹ akọwe Ijọ na nilu Zaria fun ọpọ ọdun. Ninu ọdun 1963 ni nwọn fi i joye Diakoni.

Awọn Ẹgbẹ ọmọ ibilẹ Ẹgba ati Ijọ Onitẹbọmi kinni ni ilu Zaria l'o ṣayẹyẹ idagbere fun Diakoni Ọpalẹyẹ.

Awọn alaṣẹ Ijọ na Diakoni J. O. Ogundele ati Oniwaasu Ijọ na Ẹni-ọwọ J. A. Ebo sọrọ iwuri pupọ nipa Diakoni Opalẹyẹ.

Ninu ọrọ rẹ, Diakoni Ọpalẹyẹ dupẹ lọwọ gbogbo wọn fun ifẹ ti nwọn ni si i.

Bayi, a gbọ pe Diakoni Ọpalẹyẹ ati idile rẹ ti dari sile wọn ni ilu Abẹokuta ni Ipinlẹ Ogun.

## Alaafin di Baba-Isale

APAPỌ Ẹgbẹ ti nta igi idana ni ilu Ọyọ ti njẹ Oke Aafin Firewood Sellers' Association Ọyo, ti yan Alaafin Ọyo Alaiyeluwa Lamidi Ọlayiwola Adeyẹmi Kẹta gẹgẹ bi Baba Isalẹ Ẹgbẹ na titi di ojo ti o ba waja.

Nigba ti iko enia mẹwa kan ti o jẹ ti Ẹgbẹ na lo ki Ọba na ni Aafin rẹ ni Ọyo ni nwon ṣipaya oro na fun aiye gbo. Nwon ni, yiyan ti awon yan Ọba Adeyemi si ipo na jẹ okan l'ara eto ti nwon ṣe silẹ fun ti ayẹyẹ odun kẹrin ti nwon da Ẹgbẹ naa silẹ.

Nigba ti alaga Ẹgbẹ na Ọgbẹni Ajani Lawal nsoro nibi ayẹyẹ na o ṣe alaye pe yiyan ti nwon yan Babalaafin si ipo yi jẹ imọ-riri ipa ti o nko fun ilosiwaju Ẹgbẹ na lati igba ti nwon ti da a silẹ.

Nigba ti Ọba Adeyẹmi nfesi, o dupẹ lopolopo lowo Ẹgbẹ na fun ipo ọyẹ na ti nwon gbe fun oun; o si ṣe ileri pe oun yio sa gbogbo ipa oun fun ilosiwaju Ẹgbẹ na.

Ṣaaju akoko yi, awon Ọmo Ẹgbẹ na ti yan Oloye titun fun Ẹgbẹ na fun ti ọdun yi.

Awon na ni: Alaga Ẹgbẹ Ọgbẹni Ajani Lawal, Balogun Ẹgbẹ Salawu Aṣerifa; Akapo Nusiratu Abẹo, ati Akowe Ẹgbẹ Alhaji Baṣiru Ọmo Ẹṣo.

## Sanni Dada jade l'aiye

NWỌN ti kede iku Alagba Sanni Dada ti iṣe Esinkin – Ijoko ni agbo ile Ọbajoko nilu Ila – Ọrangun lẹhin ti o ti lo ọdun marunlelaadọrin l'aiye.

Ninu ọdun 1960 ni nwọn fi jẹ Baale Ọbajoko.

Ọpọ ọmọ ati ọmọọmọ l'o gbẹhin rẹ. Ara wọn ni Jimọ Ajide ati Buraimọ Akanbi.

Nwọn ti sinku rẹ gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam.

**NIGERIA NEW STATE CO.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lọ, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

# Ara Osodi nfe Oba

ADELE fun ilu Oṣodi l'abẹ Ijoba ibilẹ Muṣin ni Ipinlẹ Eko, Oloye R. A. Mabinuori ti iṣe Baṣorun fun ilu Oṣodi ati awon Ijoye Oṣodi ti kesi Gomina Ologun Ipinlẹ Eko Ọgagun Adekunle Lawal lati tete ba won f'aṣẹ si oruko Omoye fun Ọba Oṣodi titun, ipo eyi ti o ṣofo lehin iku Alhaji A. Ajenifuja.

Nibi ipade kan ti nwon ṣe nilu Oṣodi laipẹ yi, awon Ijoye ati enia na so pe ilu Oṣodi jẹ ilu pataki kan l'abẹ Ijoba ibilẹ Muṣin ati pe, ọpolopo ohun idagbasoke ni awon fẹ dawole ṣugbon gẹgẹbi aṣa ibilẹ ilẹ Yoruba "ilu ki iwa ki o ma ni olori".

Nwon ṣalaye pe ko si ede-aiyede kankan l'ori yiyan omoye na ati pe oju Ijoba Ipinle Eko ni awon nwo nisisiyi l'ori oro na.

Ninu oro rẹ, Oloye Mabinuori so pe, gẹgẹbi Adele fun eto Ijoba ibilẹ nilu Oṣodi, oun pẹlu awon Ijoye ti ṣe gbogbo iṣe ti o yẹ gẹgẹbi ipo awon, ki alaafia ati idẹra le wa fun enia l'ori eto oba na ati pe omoye ti awon fi oruko rẹ ranṣẹ si Ijoba na ni awon enia nfẹ,

Agboroso fun awon Oloye ilu Oṣodi Alhaji K. L. Balogun ti iṣe Maiyegun ilu na so pe alaafia ilu, igbega awon enia ilu Oṣodi ati agbegbe rẹ ni o jẹ awon logun ati pe nitorina awon ro Gomina Ologun Ipinlẹ Eko, Ọgagun Samusideen Adekunle Lawal lati ba awon f'aṣẹ si oruko omoye na gẹgẹbi Ọba ilu Oṣodi.

## Eko-Ende ndawo Aafin

Awon enia ilu Eko—Ende ni Kaksul Ifẹlodun ni agbegbe Ọṣun, ni-Ipinlẹ Ọyo, ti bẹrẹ iṣẹ kiko aafin Elende Eko-Ende nipa iṣẹ oogun oju ara won.

Ni osẹ ti o koja ni nwon bẹrẹ iṣẹ na ti yio na won ni opo ẹgbẹrun Naira.

Nigba ti o nba awon enia ilu na soro nibi ti nwon yio ko aafin na si, Elende Eko-Ende Oloye Raji Ọladoṣu Ayunawa Kẹta kan saara si won fun ẹmi iṣokan won.

**KEREO**

**GBOGBO - ENIA!**

*fun*

- *Ìpolowo ọja ati Ìkede,*
- *Akiyesi ati Ìtufọ,*
- *Ìranti oku ati Ìkede Ariya,*
- *Ìkilọ ati bẹbẹ lọ;*
- *Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.*

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI:-

*Advertisement Managers:*

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496B YẸMETU ALADỌRIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (46)

A o ranti pe ni ọsẹ t'o kọja, Adeyẹmọ Ọjẹrinde royin gọngọ ti o sọ nibi ọdun aṣa ibilẹ ti a ṣekọja ni ilẹ wa. O tẹnumọ ẹwa obinrin, ijo ati are idaraya; ilu abalaiye ati orin ti nwọn kọ nibẹ. O si sọ pe, enia t'o ba debẹ l'o le mọ iyin i ro.

Ki a ma wulẹ ba ọrọ lọ bi ilẹ bi eni mọ, eyi ni iroyin Ipade won ti osẹ yi gẹgẹ bi Akowe Ipade ti kọ ọ silẹ.

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Ẹẹ ku onile o, Alayidde mi
Ayinde Ọmọ Ayoyọ ti i j'Ejigbọjọ.
O gb'ọrọ mi Ipade t'o kọja
Tabi o ko gbo ọ gidi;
O ko ri i pe gọngọ ara sọ
Nibi ọdun aṣa ibilẹ.
Iroyin na l'o gbọ yi ọmọ Ejigbọjọ.
Gọngọ so, tabi ko sọ?

Lawuyi Ogunniran

Emi ko le sọ pe gọngọ sọ,
Ng ko si le sọ pe, gọngọ ko sọ.

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

A! Ayinde ọmọ Ejigbọjọ!
Mo ti r'ibi ti o bomọ.
Aṣe, Ọlọtẹ enia ni
Mo nf'ọrọ aṣa ibilẹ lọ!
Aṣe, ẹiẹgan enia l'Ayinde
Ayinde ko n'inu didun kan
L'ori itu ti gbogbo wa npa,
Aṣe, eke enia l'Ayinde
T'o r'o o titọ nilẹ ti ko le royin!
B'Ayinde ki i ba ṣ'eke,
Bawo l'o ṣe le sọ pe,
Oun ko le sọ pe, gọngọ sọ,
Oun ko si le sọ pe, gọngọ sọ!
Ewo ni k'a gbagbọ
Ninu gbolohun ọrọ yi?
Ṣe gbogbo igbe t'aiye nke
Pe, ọdun ibilẹ nlọ lọwọ,
Ṣe iweroyin ti nke
Ati gbogbo Redio ti nsọrọ;
Ṣe, igbe ti Tẹlifiṣọn nke ko to,
T'Ayinde fi nsọ pe,
Oun ko le sọ pe gọngọ so ni?
Ẹ ko r'iwa Ayinde,
Ẹ ko r'agabagebe enia!
Ayinde maa gbọ, ọmọ Ejigbọjọ,
Bi ki i waa ṣ'ọrẹ mi too kuku iṣe
Nṣe ni ng ki ba fa ọ le onidilaali lọwọ;
Nṣe ni ng ki ba tọka rẹ
Gẹgẹ bi ọkan pataki ninu enia
Ti nbinu ọdun aṣa ibilẹ

Lawuyi Ogunniran

Ajao! duro na ki o gb'esi ọrọ.
Mo fẹ ki o tẹtibẹlẹjẹ
Ki o gb'ọrọ ẹnu mi
Ki i ṣe pe, mo nbẹru enia,
Ki i ṣe pe mo nbẹru rẹ
Ki i si i ṣe p'ọrọrẹ l'o kamọmọ
Ti mo fi fẹ fun ọ l'alaye ọrọ;
Bi koṣe nitori onkawe
Ti yio fẹ mọ itumọ ọrọ mi,
K'oluwarẹ ma waa d'elede meji enia..
Gẹgẹ bi mo ti sọ fun ọ;
Ng ko le sọ pe gọngọ sọ,
Ng ko si le sọ pe, gọngọ ko sọ.
Nitoripe, ohun t'o le jẹ gọngọ sisọ
L'oju ọpọ ọmọ araiye,
O le ma jẹ babara
L'oju ọpọ ẹda enia;
Ibi ọpọ ti ndimu
Lati wọran aṣa ibilẹ,
Ti nwọn nnawo-nara,
Ti nwọn ndaamu,
Ti nwọn si nlakaka;
Nibẹ l'ọpọ enia ti nrẹrin
Ti nwẹn nka wọn si oniran
Ti ko mọ 'hun t'o yẹ k'o f'owo ṣe
Iru ara yowu k'alaṣa ibilẹ da.
Njẹ iru ara ohun le jẹ
Gọngọ sisọ l'oju iru wọn?
Idi niyi, ẹmọ Ajiṣegiri
Ti mo fi dahun ọrọ
Pe, ng ko le sọ pe gọngọ sọ,
Ng ko si le sọ pe, gọngọ ko sọ
Iwọ ni ede ko ye,
Emi ki i ṣe eke,
Emi ki i ṣ'ọlọrọ meji enia

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Ayinde mo ti gbọ ọmọ Ejigbọjọ
Ṣugbọn mo fẹ bi ọ n'ibeere kan,
Ṣe ki ng beere,
Tabi ki ng ma beere?
Ṣugbọn ma gbagbe o;
"Ibeere ki i d'ija".

Lawuyi Ogunniran

Ng ko sọ pe ki o ma beere ọrọ
Ṣugbọn mo fẹ ki o ronu denu
Ki o to maa bi mi;
Nitori bi o ba beere ọrọ omugọ,
Ng o kan ọ l'abuku;
B'o ba di k'a ja ẹṣẹ,
Ng o fi ikuuku kọ ọ l'ọgbọn gidi;
Bo si ṣe ti atori,
Ng na ọ l'atori jinna.

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Ayinde! Yara panumọ,
Tara, tara ko ọrọ ẹnu rẹ jẹ.
Ẹgbẹ a ha maa kẹgbẹ l'ọọku?
O ko le sọ pe, o o na mi
Bi ijakdi ba de;
Bi o ko ba nii ṣ'agbere,
Nṣe ni ki o maa sọ pe,
A o d'ijọ f'ọkunrin han ara wa ni;
Nitori ọmọde gbọn,
Agba gbọn, l'a fi da'iẹ alaaye.
Ṣugbọn ibeere ti mo ni ninu
Ti mo fẹ bi ọ ni
Pe, bayi, o ti sọrọ
Pe, ohun t'o jẹ gọngọ f'ẹnikan
O le ma jẹ gọngọ f'ẹlomii
Ibeere mi ni pe,
Ewo l'aṣa ibilẹ na jẹ fun ọ ni tirẹ?
Mo mọ pe, ọlọgbọn ẹwẹ ni ọ,
Mo si mọ pe,
Aaye ko si l'oni mọ;
Ṣugbọn maa ro o titi d'Ipade t'o nbọ.

## Jackport

# 4, 5, 25

## Alaran Tips

# 5
# 17
# 38

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta ẹya ni ede Yoruba (N1) Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (N1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹẹdan Ogun enia dudu (₦5); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni ala (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 110 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box. 17 Ilorin

# Kelani Yusuf ati are Igunnuko

BI o tilẹ jẹ pe, orisirisi awo alare Igunnuko ni o ti gb'ode kan bayi, sibẹ "Ọlọtọ ni ti oun ọtọ" ni are Igunnuko ti gbajumo ati Olohun – iyo nni, Kelani Yusufu ṣẹṣẹ ṣe jade eyiti o pe ni "Kelaani Akande ati awon alare Igunnuko rẹ."

Ile–iṣẹ ADETUNJI OMỌ AJE SOUND STUDIO ni o tẹ awo na jade eyi ti gbogbo enia ti beresi dura bi akara gbigbona bi won ba ti ngbo o s'eti.

Gẹgẹ bi gbogbo enia ti mo, Ọgbẹni Kelani Yusufu jẹ alare atata,

LATI ỌWỌ ONIFAAJI

ẹni ti o nkorin ti o mu ogbon dani ati pe, ko si ona ti ko le gba fi korin Sakara. Eyi ti o ṣẹṣẹ ṣe ti a nrohin yi naa pabanbari, ti o fi jẹ pe ibi ti nwon ba ti ntẹ awo na, pelemo ni awon enia maa nbo ibẹ lati gbo o.

Awo Kelani Akande pẹlu are Igunnuko yi dun pupo, ko si eyi ti ko gbẹiyẹ mo awo are Igunnuko ti nwon ti nṣe bo wa lọwọ. Ilu ti o dun ni ki a wi ni tabi orin pẹlu ohun awon elegbe? Bi enia ba jẹ omo Tapa ti o ngbo orin na, ori oluware yio maa dide ni. Bi eni ti ki iṣe omo Tapa na ba ngbo o yio maa ran lo bi okoto ni. Are inu re je "a dun bi agbayun" fun gbogbo eni ti o ba leti.

Irohin ko to afetigbo ni are Igunnuko ti Kelani ṣe sinu awo] na, o dun lati pa ironu re. Are na si tun mu faaji peleke.

Gege bi Ọgbeni Kelani ti wi ninu awo na pe "Igunnuko yẹ mi" ati "Awa l'agba ninu Tapa": ni ti gasikia ododo ni oro na, nitope o fi agba han ninu are na.

Bi o ba fe ra a, o ti wa kakiri Ṣoobu rekodu nibi gbogbo. Nomba rekodu na ni OLPS 0117, tabi ki o lọ taara si ADETUNJI STORES Ibomo St. lẹba Ita Agarawu,Eko ati ni ADETUNJI HOUSE, Popoyemoja, Ibadan.

27



ỌBA AJAGUNGBADE KẸTA
Sọhun Ilu Ogbomọṣọ

## Oyo jare ofo ile

ADAJỌ Ile ẹjo giga kan nilu Ibadan, Ọlola Ganiyu Agbaje ti fagile ofin kannpa ti Ipinlẹ Iwo Oorun atijo eyi ti Gomina Adeyinka Adebayo ṣe lati fi yan Igbimo ti ngbo ẹjo aala ilẹ ni Ipinlẹ na.

Ninu odun 1968 ni nwon yan Igbimo na. Adajo ile ẹjo giga na so pe ofin kannpa ti nwọn fi da Igbimo na silẹ ko ba ofin mu, iṣẹ ti Igbimo na ṣe ko si ba ofin mu pẹlu.

Nitorina, Adajo Ọlola Agbaje so pe, bakanna ni oun fagile idajo ti ile ẹjo Kotẹmilorun ti o tun gbẹjo na ni Iwo - Oorun atijo ṣe pe, ko ba ofin mu.

Nilu Ibadan ni Ọlola Agbaje ti ṣe idajo na l'ori aga rẹ nigbati o ndajo l'ori ẹjo ti Alaafin Ọyo, Ọba Lamidi Ọlayiwola pe Ṣohun Ogbomoṣo Ọba Ọladunni Ajagungbade l'ori aa'a ile]laarin ilu mejeeji

Ọba Adeyẹmi l'o nrọ ile ẹjo giga na lati fagile abajade Igbimo Ogundare, ti ile ẹjo kotẹmilorun ti ngboro aala ilẹ ati ofin gan-an ti nwon fi gbe Igbimo aala ilẹ kalẹ.

Ninu ẹjo Alaafin, Agbẹjoro rẹ, Oloye Rotimi Williams nrọ ile ẹjo giga lati paṣẹ pe, Ijoba, Ṣohun Ogbomoṣo, Kansul Ogbomoṣo tabi iranṣẹ won ko gbodo dori ilẹ ti Igbimo aala ilẹ ati ile ẹjo kotemilorun na gbe fun won.

Ninu idajo rẹ ti o waiye ni ojo kokandinlogbon oṣu kinni odun 1971, ti ile ẹjo kotẹmilorun si tun faramo ni ojo kejila oṣu kẹsan odun 1973, ilu Ogbomoṣo ni a dalare pe Ipẹba ni ki o jẹ aala laarin ilu mejeeji.

Ninu idajo re ti o ṣe nilu Ibadan ni ojo Aje ti iṣe ojo kejidinlogbon oṣu keji odun yi, Ọlola Agbaje so pe, ofin kannpa ti odun 1968 ti a fi gbe Igbimo aala ile na kale ko ba ofin mu, bee ni idajo kotemilorun lori re pelu ko ba ofin mu.

Nitorina, Ọlola Agbaje so pe, oun da Alaafin l'are; ki Ṣohun Ogbomoṣo lo san otaleerugba o din eewa Naira (₦250.00) owo irinsẹ fun Alaafin ati pe,Odo Ọba ni aala bayi laarin Ọyo ati Ogbomoṣo.



## Aworan Asa Ibile

AWORAN Ẹgbe yi nṣe afihan ara won enia ti o nipa ninu ayeye aṣa ibile ile Adulawo ti o koja lo yi, eyi ti nwon ṣe ni ile Naijiria

Awon omobinrin na ti e nwo yi ni a ya ninu are onijo kan ti nwon ṣe ni akoko ajodun na. Are yi je okan ninu oniruru are ti nwon ṣe ni akoko ayeye na. Bayi are ti pari, olukuluku si ti gba ona ilẹ rẹ lo.

## Ijo Selesia

(Lati Oju Ewe Kinni)

Ṣugbọn bayi, Iya Ijọ na ko wa sibi ile itaja re nibẹrẹ ose yi bee ni pabo ni gbogbo aniyan onirohin wa lati ri Iya Ijọ na nja si:

Enikan ti o sunmo Iya Ijọ na pẹkipẹki ṣugbọn ti o kọ lati sọ oruko ara rẹ, so fun onirohin wa pe ilu Eko ni Iya Ijọ na lọ l'ori ohun ti oun ro pe o nilati jẹ l'ori iṣẹlẹ na.

Irohin miran ti o tun ṣẹṣẹ tẹ wa lọwọ l'ori iṣẹlẹ na fi ye wa pe Iya Ijọ na ti pada si Ibadan lati Eko ṣugbọn Baale rẹ ko ti i de ati pe o nilati jẹ pe, o nba awọn kan ninu aṣaaju Ijọ Sẹlẹṣia nilu Eko sọrọ ni. Titi ti a fi ngbe iwe wa lọ sori ounte, onirohin wa ko ti ri Iya Ijọ na ba sọrọ.

## Yanmuyanmu

(Lati Oju Ewe Kinni)

oogun na wa.

Irohin fi ye wa pe, idigbolu awọn ẹfọn na ti da ipaiya, ẹkun ati ibanujẹ silẹ ni ilu na, eyi ti o mu aibalẹ – ọkan ba awọn alaṣẹ pẹlu.

Nitori ọrọ yi, Mairagi ilu Lọkọja, Alhaji Yahaya Muhamodu ti paṣẹ fun awọn Musulumi ati Onigbagbọ ilu na lati wọle adura pe ki Ọlọrun ba wọn pana iyọlẹnu awọn ẹfọn na.

Irohin fi ye wa pe, oniruuru ọna ti awọn ara ilu na mọ ni nwọn nlo lati bori agbako na. A gbọ pe ọpọ enia l'o ti dawo maluu jọ lati fi ṣetutu l'ori ọrọ na: bee ni awọn oloogun ti o da ara wọn l'oju paapaa ti bẹrẹ si i sa ipa wọn l'ori ọrọ na.

Alakoso ọran alaafia ilu fun Lọkọja, Alagba J.O. Onietan sọ pe, ododo ni irohin na pe, ẹfọn nja ilu Lọkọja l'ogun; o ni o ṣe oun ni kayeefi pupọ bi awọn ẹfọn ṣe ṣe bẹẹ yawọlu bi ogun ọwọkan. O ni l'oni ọjọ karun oṣu kẹta ọdun yi ni eto ipolongo fun alaafia ilu yio tun bẹrẹ l'ọtun.

Alaga Kansul Kogi labẹ eni ti Lọkọja wa, Alhaji A. K. Ibrahim paapaa sọ pe, nṣe ni awọn ẹfọn na yawọlu. O ni oun ko gbọ iru rẹ ni itan ri ni ilu Lọkọja.

## Eto Agbayanu

(Lati Oju Ewe Kinni)

oun yio mu sa l'oogun.

Siwaju si i, Oloye Lajide sọ pe a o gbe Igbimọ kan dide laarin awọn Kansilọ; iru Igbimọ bẹ ni yio si maa gba Kansul oun ni imọran l'ori eto ilọsiwaju gbogbo ti o ba yẹ fun ilu Ogbomọṣọ nile ati loko.

Nigbana ni Oloye Lajide rọ awọn enia Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ lati jaramọ sisanwo ori wọn ki Kansul na ba le r'owo na lori iṣẹ gbogbo ti o wa niwaju rẹ, o si rọ awọn enia na pẹlu lati fọwọsowọpọ pelu rẹ.

## Ọdun Okebadan

NI ọjọ kẹta oṣu yi ni Abọke tuntun fun ilu Ibadan, Oloye Agbọọla Akanmu Kilanko bo Okeebadan, nibi ti okẹ aimoye awọn omode ilu lokunrin lobinrin ti tẹlẹe.

Onirohin wa fi ye wa pe Aboke ti Olubadan ro l'oye, Ọgbẹni Ọlaopa Ọpakunle ti o ti nleri tẹlẹ pe oun yio bo Okeebadan dandan, ko le yoju s'ode mo.

Kaka bee, ile ẹjọ giga ilu Ibadan ni a ti gburo rẹ pe o lo pe Olubadan Ibadan, Igbimo rẹ ati Aboke titun l'ẹjọ pe ki ile ẹjọ paṣẹ pe Olubadan Ibadan ko lẹtọ lati jẹ Aboke miran dipo oun lai bun ẹbi oun gbo. Ọjọ kẹsan oṣu yi ni ẹjọ yio bẹrẹ.

## Pools !

**Nap**

SIR SIMPLE ADE NAP
N4/752b Yemetu Aladorin Ibadan
No 22xxbk 41xxbk
Fun Week 32

16
27
50


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE OR RE DE
A TI GBE TANA DANU
A TUN GBE OMIRAN DE
A TI NI ẸRỌ ATATA YI:



## Cassava Grater

(WITH JLỌ L101 ENGINE) **(₦350.00)**

(EYI NI ẸRỌ TI NWỌN FI NRIN GARI OLOWOYỌ)

Aiye ti di jẹlẹnkẹ,
Ko si ki a maa fi agbara wa owo mo
Bi o ba ti ni ẹro yi kanṣoṣo
Jẹ ki okan rẹ balẹ pẹsẹ
Nitoripe owo-nlanla
Ni iwo yio maa pa.
Owo ẹro na ko po rara
₦350.00 pere ni.
Ẹ maa bo taara si:

## Western Nigerian Technical Company Limited

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

WENTEC 1955


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/[illegible] Yemetu Aladorin P. M. B. [illegible] Ibadan. [illegible] (Editor) [illegible] Lagos Office: 16, Odunlami St. Phone [illegible]